# OBINRIN KAN NIBI KANGA

**Johannu 4:1-42**

**ẸKỌ 30 - FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ẹnyin o si fi ayọ̀ fà omi jade lati inu kanga igbala wá" (Isaiah 12:3).**

## Samaria

Nigba gbogbo ni Jesu maa n mọ̀ ibi ti awọn eniyan ti wọn jẹ olooototọ, ti wọn yoo si fi eti si iwaasu Rẹ̀ wà. Bi o tilẹ jẹ pe o jẹ ọna ti o kuru, awọn Ju ki i maa n la aarin Samaria kọja nigba ti wọn ba n ti Jerusalẹmu lọ si Galili, nitori wọn korira awọn ara Samaria. Ni ọdun pupọ sẹyin, nigba ti a kó awọn Ju lọ si igbekun, a mu awọn baba nla awọn ara Samaria wa lati gba orilẹ-ede wọn: nitori eyi, awọn Ju korira wọn. Awọn ara Samaria jẹ abọriṣa; nigba ti wahala de ba wọn, wọn ro pe awọn ọlọrun ilẹ naa n binu, nitori naa wọn pe diẹ ninu awọn alufaa Ju, lati kọ wọn nipa Ọlọrun otitọ. Sibẹ wọn ko fi iwa abọriṣa wọn silẹ patapata, nitori naa ni awọn Ju ṣe gba wọn si alaimọ́.

Ṣugbọn Jesu mọ pe ẹni kan wà ni Samaria ti yoo dahun ipe Ihinrere, nitori naa Oun "kò si le ṣaimá kọja larin Samaria." A maa n gbọ ni igba miiran pe Ọlọrun yoo mi Ọrun on ayé lati gba ọkàn kan là, eyi ti o fi han wa bi O ti ro igbala wa si ohun pataki tó.

A ranti pe Filippi n ṣe isọji lọ ni Samaria ni igba kan. Lai ṣe aniani, ọpọlọpọ eniyan ni o wa ninu ipade rẹ: ṣugbọn laaarin wọn gan an ni Ọlọrun sọ fun Filippi pe ki o sọkalẹ lọ si aṣalẹ Gasa. O dabi aṣẹ ti o ṣe ajeji, ṣugbọn Ọlọrun le ri i pe Filippi yoo pade ọkunrin kan nibẹ ti ebi igbala n pa. Filippi pade iwẹfa ara Etiopia naa o si kọ́ ọ bi o ti le ri Jesu. Bayii ni o jere ọkan iyebiye miiran fun Kristi.

## Jesu Nibi Kanga Jakọbu

Jesu ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ti rin mile pupọ ni akoko ti wọn de ibi kanga Jakọbu, wọn si ṣe alai ni ounjẹ. Nigba ti awọn ọmọ-ẹyin lọ si ilu lati ra ounjẹ Jesu sinmi leti kanga naa. Gẹgẹ bi a ti kọ́ ninu ẹkọ wa ti o kọja, awọn kanga diẹ ti o wa ni agbegbe aṣalẹ ti o si mooru yii jẹ iṣura iyebiye ti a ko le diyele, ti o si ṣe pataki lati mú ni wa laaye. Jesu lo eyi gẹgẹ bi àtẹ̀gùn ọrọ Rẹ̀ nigba ti O ki obinrin ti o wa pọn omi lati ilu, nigba ti O n sinmi nibẹ.

Nigba ti Jesu bẹrẹ ọrọ sisọ nipa bibeere omi lọwọ rẹ, O fi han pe ko ro ara Rẹ̀ si ẹni ti o dara ju lati ba obinrin yii sọrọ. Kò si ohun ti Kristi ki i ṣe akiyesi. Kò si ẹlẹṣẹ ti o buru ju ti Jesu ko le gbọ igbe rẹ fun aanu. Kò si iṣoro wa bi o ti wu ki o kere to, ti jesu ko ni mọ nipa rẹ ki O si ran wa lọwọ lati bori rẹ. Jesu sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe: "Ologoṣẹ meji ki a ntà ni owo idẹ kekere kan? bẽni ko si ọkan ninu wọn ti yio ṣubu silẹ lẹhin baba nyin….Nitorina ẹ ma foiyà; ẹnyin ni iye lori jù ọ̀pọ ologoṣẹ lọ" (Matteu 10:29, 31). Jesu gbe laaarin awọn talaka, ti wọn fi ayọ gbọ ti Rẹ̀; O si ba awọn agbowode jẹun, awọn ẹni ti awọn Ju kẹgan. Jesu mọ ọkan eniyan, bi O ba si ri ifẹ kan nibẹ fun otitọ́, ko si ẹni ti o rẹlẹ ju fun Un lati ran lọwọ. "Enia a ma wò oju, Oluwa a ma wò ọkan" (I Samuẹli 16:7).

## Omi Iye

Nisisiyii, Jesu ni anfaani lati sọ nipa Omi Iye ti O ni lati fi fun ni. Nigba kuugba ni a maa n fi Ẹmi Ọlọrun we omi iye ninu Iwe Mimọ́, a si kà pe ni ọjọ nla ikẹyin ti ajọ, Jesu duro, O si kigbe wi pe: "Bi òrùngbẹ ba ngbẹ ẹnikẹni, ki o tọ mi wá, ki o si mu. Ẹnikẹni ti o ba gbà mi gbọ́ … lati inu rẹ̀ ni odò omi ìye yio ti ma ṣàn jade wá" (Johannu 7:37, 38). Nihin, O n sọ nipa Ẹmi Ọlọrun ti yoo wà ninu olukuluku onigbagbọ́ tootọ nigba ti o ba ri igbala, ti yoo ṣan jade ki gbogbo eniyan le rì i pe o ti wà pẹlu Jesu, o si ti kọ nipa Rẹ̀.

Ohun ti Jesu sọ ko ye obinrin ara Samaria yii. Dajudaju, ko si ẹni ti o tobi ju Jakọbu ti o wa kanga yii jin to -- iwọn ọgọrun ẹsẹ le marun -- kọja apata ati iyanrin si isalẹ, lati inu eyi ti a ti n fa omi jade lati nnkan bii ẹgbaa ọdun! Ṣugbọn bi o ti ṣe iyebiye to o ni, fun igba diẹ ṣa ni omi yii n pa oungbẹ. Eniyan ni lati tun maa wá nigba gbogbo lati pọn ninu rẹ.

Nigba ti Jesu sọ fun obinrin naa pe oungbẹ ko tun ni gbẹ ẹ mọ, bi o ba mu ninu omi ti Oun yoo fun un, obinrin naa fẹ ẹ. Ẹru rẹ yoo fuyẹ bi oun ko ba tun ni rin ọna elekuru ti o mooru yii lati wa pọn omi mọ. Ṣugbọn Jesu n sọ nipa awọn nnkan ti o tobi ju eyi lọ, o fi eti silẹ, o si gba A gbọ́.

Ọpọlọpọ igba ni awọn eniyan maa n wa sọdọ Jesu fun ibukun ti ara – fun iwosan ara wọn, tabi iranwọ miiran, ṣugbọn ti wọn ki i fẹ fi ẹṣẹ wọn silẹ. Nigba ti awọn ọpọ eniyan ṣun mọ Jesu, lẹyin ti O ti bọ ẹgbẹẹdọgbọn (5,000) eniyan, O sọ fun wọn pe ki i ṣe nitori Ọrọ ti Oun sọ ni wọn ṣe n tẹle Oun bi ko ṣe nitori pe wọn ti jẹ akara ati ẹja. A ri ọpọ awọn eniyan bẹẹ lonii.

## Ohun Ti A Ni Lati Gbagbọ́

Nigba ti Jesu bẹrẹ si tu ẹṣẹ ti o wa ni igbesi-aye obinrin ara Samaria yii, ko binu si i. O gba pe woli ni Jesu i ṣe, awọn ibeere wa lọkan rẹ nipa ọran ẹsin, o si bi I leere nisisiyii pe ki O dahun wọn. Awọn Ju wi pe Jerusalẹmu ni ibi ti o yẹ lati sin Ọlọrun, ṣugbọn awọn ara Samaria ti kọ Tẹmpili kan si ori Oke Gerisimu. Ewo ni o tọna? Ki ha ṣe Ọlọrun kan naa ni wọn n sin?

Awọn eniyan maa n beere lonii pe, "Bawo ni mo ṣe le mọ ile-isin ti o dara? Pupọ ni nnkan ti awọn eniyan gbagbọ́, ti wọn si yatọ si ara wọn, ṣugbọn olukuluku ni o si gbà pe eyi ti awọn gbagbọ ni o tọna." Jesu ṣe alaye isin tootọ fun un. Igbala jẹ ti awọn Ju, nitori pe lati igba Abrahamu ni wọn ti jẹ ayanfẹ Ọlọrun. O si ti ṣeleri pe lati inu wọn ni a o ti bukun fun gbogbo idile aye. Jesu ni imuṣẹ asọtẹlẹ naa, O si ti wà nitosi lati bukun fun – ati awọn ara Samaria pẹlu. **Ibi ti** awọn eniyan ti n sin ki i ṣe ohun ti o ṣe pataki to bi i ọna ti wọn n gba sin; wọn gbọdọ sin Ọlọrun "li ẹmi ati li otitọ."

Ni igba kan, Ọlọrun sọ nipa awọn ọmọ Israẹli pe, "Awọn enia yi ti n fi ẹnu wọn fà mọ mi ti nwọn si nfi etè wọn yìn mi, ṣugbọn ti ọkàn wọn jìna si mi" (Isaiah 29:13). Lẹyin naa Jesu sọ ọrọ kan naa fun awọn Ju, O si fi kun un pe: "Lasan ni wọn ntẹriba fun mi, ti nwọn nfi ofin enia kọ́ni fun ẹkọ́" (Marku 7:6, 7). Ọlọrun n fẹ ki awọn ọmọ Rẹ̀ "gbé ọwọ mimọ soke, li aibinu ati li aijiyan." Wọn gbọdọ sin In pẹlu "ọwọ mimọ, ati aiya funfun." Kò si aye fun ẹṣẹ ni igbesi aye ọmọlẹyin Jesu. Nigba ti ẹni kan ba ri igbala ati isọdimimọ, yoo ni ọkan funfun naa.

Obinrin ti o wa nibi kanga yii ti gbọ pe Messia yoo wá, o si dabi ẹni pe o gbagbọ pe ibukun Rẹ̀ yoo wà fun gbogbo eniyan, nitori ti o wi pe, "Nigbati on ba de, yio sọ ohun gbogbo fun wa."

Wahala ti o wa fun ọpọlọpọ eniyan ni pe wọn ki i fẹ ki a sọ "ohun gbogbo" fun wọn. Wọn ki i fẹ ki Jesu fi ẹṣẹ wọn han wọn. Ṣugbọn obinrin yii n fẹ lati gba ẹbi ẹṣẹ rẹ, nitori o mọ pe Jesu ni Kristi naa, Ẹni ti yoo wá.

**Obinrin Ajihinrere**

Nigba ti Oluwa ṣe iyipada ni igbesi aye rẹ o fẹ ki awọn ẹlomiran mọ nipa rẹ. Eyi ni ami ti o daju nipa iyipada ti o pe. Nigba ti Jesu ba gba ọkan wa là, ti O si fun wa layọ, a maa n fẹ ki awọn ẹlomiran mọ nipa rẹ, ki wọn le ni ayọ pẹlu. Ọpọlọpọ eniyan gba obinrin naa gbọ, wọn si jade wa si ibi kanga lati ri Jesu. Lẹyin igba ti wọn gbọ ọrọ Rẹ̀ wọn wi pe "Ki iṣe nitori ọrọ rẹ mọ li awa ṣe gbagbọ: nitoriti awa tikarawa ti gbọ́ ọ̀rọ rẹ, awa si mọ̀ pe, nitõtọ eyi ni Kristi na, Olugbala araiye." Olukuluku eniyan ni o le mọ Jesu funra rẹ -- ki i ṣe lati mọ nipa Rẹ̀ lasan, ṣugbọn lati ni ibarẹ ati ibalo pẹlu Rẹ̀ ati lati gbe igbesi aye ti yoo wu U lojoojumọ.

Awọn ara Samaria wọnyii fẹran Jesu, wọn si bẹ Ẹ pe ki O ba wọn jokoo. O si ba wọn jokoo fun ọjọ meji. Bawo ni wọn ti yatọ si awọn ara Gadara tó, laaarin awọn ẹni ti Jesu ti wo ọkunrin ẹlẹmi eṣu ni sàn. Awọn ara Gadara bẹ Ẹ pe ki o kuro ni agbegbe wọn – Ẹni ti O ti ṣe iṣẹ oore ti o ya ni lẹnu bẹẹ fun ọ̀kan ninu awọn eniyan wọn!

Awọn ọmọ-ẹyin n ṣe aniyan nipa Jesu nitori ko ti i jẹun, ṣugbọn O sọ fun wọn pe ounjẹ Oun ni lati ṣe ifẹ Baba – eyi ni lati sọ fun awọn eniyan ọna ti wọn le fi bọ lọwọ ẹṣẹ wọn. Idi ti O fi wa si aye ni lati ra ọkunrin ati obinrin pada sọdọ Ọlọrun, ki wọn ba a le mura silẹ fun Ọrun.

**Awọn Alagbaṣe Ko To Nnkan**

Igba gbogbo ni a maa n gbọ ọrọ yii pe, "Ikore pọ̀, ṣugbọn awọn alagbaṣe kò to nkan," itumọ eyi ni pe ọpọlọpọ ọkan ni o n fẹ igbala, ṣugbọn awọn Onigbagbọ tootọ ti o n gbe asia Ihinrere soke kere pupọ, awọn ti wọn ti mura tan lati fi igbadun aye du ara wọn ki wọn ba a le ṣiṣẹ fun Jesu. Titan Ihinrere igbala kalẹ gbọdọ jẹ pataki fun wa ju jijẹ ounjẹ ti ara lọ. Nigba ti a ba jẹ ounjẹ wa, ebi yoo tun pa wa lai pẹ, ṣugbọn iṣẹ ti a ba ṣe fun Jesu ni o jẹ ere ayeraye fun wa ni iye ainipẹkun.

## AWỌN IBEERE

1 Njẹ o ro pe o ni idi ti Kristi fi gba aarin Samaria kọja?

2 Ki ni orukọ mẹta ti obinrin yii fun Kristi?

3 Njẹ Kristi fi Ẹni ti Oun i ṣe han an?

4 Njẹ awọn ara ilu naa gba ẹri rẹ̀ gbọ́?

5 Ki ni ṣe pataki ni igbesi aye Kristi ju ounjẹ ti ara lọ?